# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODE."—W. T. STEAD.

VOL. II. NO. 94. SATURDAY, APRIL 26, 1924. FOURPENCE.



## DURO THOMAS.

55, MASSEY STREET, LAGOS, (NIGERIA.)

P.O. Box 374. Telephone No. 243.

*The Best House for every Description of German Goods.*

**"Specialities: Enamelware, Beer, Wine, Iron Bedsteads, Ruby Plates, Rubber Beads of all kinds, Clay and Briar Pipes, Champagne, Cement, Biscuits in cases, Gun Powder, Wire Nails Raugoon and original Ballam Rice, Accordeons, Piano, Padlocks, Beads, etc., etc., etc."**

---

N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.

***J. F. SICK*** ati AWỌN ẸGBẸ.

No. 7, Ita Ibode lalai, l'eti *Glover-Memorial Hall, (Customs Street,)* EKO.

29 APR 1924 LAGOS





Awọn Oyinbo Onișowo yi nranșẹ MASINI-ARANSO ti a npe ni VESTA Nos. 1-4 t' ọlwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju, a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-owo yi.

Nwọn mura tan lati șe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ranșẹ Mejila tabi jubẹ lọ ninu MASINI na.

Awọn Oyinbo yi nșẹ orișiriși Ilẹkẹ alarabara, nwọn si nranșẹ *Cement* ati panu kikọle to nipọn, ati ẹja abọmafọ ati orișiriși ọja.

Ilẹkun Ile awọn Oyinbo yi și nigbakugba ti ẹnia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ ASIRI nipa OWO. IROHIN KO TO AFOJUBA.

**J. C. VAUGHAN**

Ti Ile-Oja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Oja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun aikọle fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorişirişi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn onişowo Irin Işẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ ọ.

**M. D. MARTINS**

23, SCALE SQUARE, LAGOS.

Ọgbẹni yi jẹ ẹniti o nṣe ọti orişirişi. Ginger Ale, Şile mẹta abọ (3/6) fun Doz. kan ninu Igo Beer, ati Şile mẹta (3/-) fun ẹniti o ba fẹ ra pupọ bi Dozen marun (5 Doz) ati ju bẹ lọ.

Lemonade bakanna, Cider Champagne bakanna Soder Water ninu Igo kanna Şile kan ati Nain (1/9)

O npọn ọti ni Jebba Street, Ebute Mẹta.

Cable Address:—
"Steinafrik" HAMBURG.

**E. H. STEIN & Co.**

HAMBURG, Neurwall 16/18,
Hildebrandhaus.
*AFRICAN MERCHANTS.*

***ALL INDENTS EXECUTED.***

for
English and Continental Goods
and
PRODUCE
Sold on Best Terms.

**Produce to Europe covered by Floating Marine Insurance Policy.**

*P. O. Box No. 505.*

Agent in Lagos:—

**Mr. Karimu Kotun**

Broad Street, & Portonovo Market Store.

ẸNIKEJI,

Aşọ Oke to yanju mbẹ lọdọ Iya Afin Saamọta Ikẹ Ọlọrun fun tita, ọpọku Ọyọku ni owo wọn, lọ bere ni 3 St. John Street, l'Eko, leti ile Johnson Agbẹjọro.

# ERO YA WA RA.

ADEBOYE ŞOLANKẸ Onişowo "Gbabiọgẹdẹ" nta Panu-kikọle ati kikan-ọkọ, Igo lorişirişi, Kọkọrọ (Işika) t'ilẹkun ati t'apoti lorişirişi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọda lorişirişi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun-ẹrọ, ati Ọşan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorişirişi, Awo ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-şawa l'okun ati Ẹja Abọmafọ, ni Ile-ọja rẹ ni No. 4, Idunmagbo Street, (l'ebute Olowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, (l'Anikantamọ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Irin-işẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

OWO ỌJA RẸ FANIMỌRA,

Ẹ LỌ RA TIYIN NIBẸ.

*Editor & Proprietor*:—
ADEOYE DENIGA,
*Offices*: 22 & 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILE NI OWO GBIGBA RẸ.

| Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|
| Ọdun kan 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

:o:

YABA ILE AGBADU.

A gbọ pe bi Hausa kan ti nda Malu bọ wa si Eko ni lọlọyi lati Yaba, bẹni ejo oloro kan ti o l'ọpọ to ọrun ẹsẹ ọmọ-titun, ti o si dudu si, fo mọ ọ, ṣugbọn lọgan bẹni Hausa na fi igi ti o nfi nda ẹran rẹ lọ lori tutu, a sọ pe irufẹ ejo bayi wọpọ ni Yaba ati agbegbe rẹ, Ọlọrun ṣọ ni!

O YẸ O, ON'ILE NLA TI MB'OLE LẸRU.

Ko si botiri ni awówo niba abọwọde ti ọrẹ wa Ọgbẹni Augustus Scott ọkọnrin-jẹjẹ A-bi-ja-kunkun, ti Ile-Ọwọ Alalumọgaji (*John Holt & Co.*) ṣe ni arọ *Thursday* ọsẹ yi, nibati o ṣi ile titun kan ti Baba Oke moranlọwọ lati kọ si Ita *Ricca*, Okepopo, ni ilẹ yi, Alufa M. S. Cole ọkọnrin tunfun-bi-agbado ti Ṣọṣi Alagogo lo wa sure si ile na, ti o si tọrọ ibukun Oluwa sori rẹ; lẹhin eyi ni awọn "Janma" da ṣẹria fun ṣẹrẹkẹ ṣin ti a ti pese sori tabili de wọn; ninu awọn ojulumọ ati Bọkini ti o wa ba ọrẹ wa yi ṣajọyọ l' eyi:—

Alufa M. S. Cole, awọn Ọgbẹni George da Costa, Ọga oni fọto, *Lawyer* Adeyemọ Alakija, Ọpẹlẹngẹ, *Lawyer* Latunde Johnson, Adara-bi-ẹrin, Albert Williams ti Ibode, E. Lewis Williams, ti ibi iṣẹ ọba l' ọdan, E. Bankọle Beckley, Ajiṣẹfinni, E. T. Scott, H. H. King, Akuruyẹjo, *Lawyer* Ọbafemi, Ajanaku-biru-ba-nba, A. A. Ọbafẹmi, Abi *Collar* ara lọtọ; H. B. Phillips, Ọkọnrin kọkọbọtọ, M. Ade. Smith Af'abẹrẹ ṣe-ni-lore, Claudius Kasumu, Af'ọmọde ṣebi agbalagba, Kuṣika Taylor, Adu-ma-dan, Duncan, Ẹlẹrọ Ọba, E. C.

Taiwo, Agbojọ lọwọ iku, *Editor* "*Eko Akete*", ati awọn Jakanjakan miran.

Awọn ẹbi ọrẹ wa yi, si ṣe bi arira nijọ na, awọn bi Iya Afin Frances Scott, Arọmadahun obirin ati Iya afin Scott, laika awọn Iyawo ile, Ile na a tu, a ba o, Aṣẹ.

AKINTUNDE ADEṢIGBIN, ỌKANṢOṢO-ARABA T'ẸGBA OṢUNṢUN; DAWODU NINU AWỌN ẸLẸRỌ ITẸWE, E KU PAMỌ O.

A mọmọ ki a to di iwoyi ki a to sọrọ diẹ nipa ipamọ ti ọrẹ wa Ọgbẹni Akin Adeṣigbin, Ọga Ẹlẹrọ Itẹwe Tika-Tore nṣe nisisiyi lati lọ si ilu Oyinbo: bi Oluwa ba fẹ. Ọrẹ wa ọloyaya na yio ṣikọ ninu oṣu to mbọ lati lo foju kan Ọba *King* ninu iran arakuyamu ti gbogbo aiye nrọ lẹkẹ lati lọ wo lọdunni nibẹ.

Ko si ẹniti o le ba ọrẹ wa yi lo ti kọ yio sọ ti ẹmi-iwa-bi-Ọlọrun ti o ni si ẹnikẹni, t'ọmọde t'agbalagba: iwa yi si ti mba bọ lati igba ewe rẹ ti a le jẹri si lọpolopọ lati igbati awa ati on ti jẹ ọmọ ile iwe kanna pọ ni ile iwe Alapako (*St. Peter's School*) ni ilẹ yi, labẹ Olukọni ni, Ọgbẹni Elkanah J. Williams Ologbe: lẹhin eyi a tun ni anfani ati tun ṣe ọmọ ile'we kanna pọ ni Ile-iwe giga ti awọn *C.M.S* (*C. M. S. Grammar School*) ni igboro ilẹ yi labẹ Olukọni Onitara ni, Alufa J. S. Fanimokun ologbe.

Lẹhin i bati o jade ni Ṣukuru, o lọ kọṣẹ Iwe-titẹ labẹ J. P. Jackson ologbe ati Oni'we-irohin *Lagos Weekly Record*, ọrẹ wa na si tun ni anfani ati ṣiṣẹ nibiyi pẹlu Prince Ladapọ Ademọla nigbati *Prince* na nṣe *Journey-man* lọdọ ọga wọn nigbana, ẹniti o di Ọba Alake Abẹokuta nisisiyi (Kabiyesi!!!) bẹlori, a njọrin, a kọ m'ori olowo: a ranti iwa ayan ti ọrẹ wa yi ni nigbati o wa ni ọmọ-iṣẹ; bi a ti nsọ yi on papa yio ranti iṣẹ wàràwàrà kan ti ọga wọn ni ki gbogbo wọn wa ṣe ni ọjọ ọsẹ kan (igbana *Office Record* ṣi wa ni *Broad Street*) kẹte lẹhin igbati aisan ulanla yen fi fi Ọba *King Edward* Keji silẹ ni ọdun 1904, ti o fi te Waya Idupẹ si gbogbo awa ọmọ rẹ

kakiri ode aiye: lẹhin eyi, ọrẹ wa lọ ṣiṣẹ ni ti Ẹrọ-Itẹwe Ọba nilẹyi (*Government Printing Office*) o si ni iye ọdun ti o lo nibẹ ki o to wa da iṣẹ tirẹ papa silẹ ninu oṣu *October, 1910*, o si jẹ ohun ayọ ati igberaga wa lati sọ pe Iwe-irohin oṣoṣu ti a nṣe nigbana ti o njẹ *The New Age Herald* ni ede Gẹsi lo kọkọ fi bẹrẹ iṣẹ rẹ nigbati o di Ọga-agba tan: a le sọ igba pupọ ti t'awa-t'irẹ nlọ fi ara gba otutu ni *Post Office* atijọ ni Ibode ti a nlọ "de 'sun" bi awọn irin iṣẹ rẹ toku nigbana de tabi ko de. A!!! Ọjọ nlo a ntọ ọ; ni 31st March, 1918, (*Sunday* ọjọ *Easter*) ni ọrẹ wa yi ṣi ile-iṣẹ rẹ titun si *Market Sreet*, nibi (ọjọ na gan si ni Pastor A. Adedeji Iṣola fi idi Ijọ Brotherhood kalẹ, ẹnikeji ẹ ko ri iṣẹ Oluwa? Ekinni njẹ Eman, ekeji njẹ Eman, nipa orukọ Oyinbo wọn.)

Nigbati a si bẹrẹ *Eko Akete* yi, kọ ṣẹhin rẹ; iranlọwọ ti o ṣe fun wa ti o si nṣe lọwọlọwọ yi nipa iṣẹ na ko ṣe fi ẹnu sọ tan. Njẹ Iwọ Ẹni ati Ọrẹ-wa-totọ, Iwọ a lọ rere, Iwọ a bọ rere, Aṣẹ, ayunlọ ayunbọ lọwọ nyun ẹnu, Aṣẹ, Ori ki fọ Awun, aiya ki dun igbin, okuta inu-omi ki ṣ'ojojo, Iwọ ko ma ri "dasi" kan talọ tabọ rẹ. Baba yio si fi Abo Rẹ kẹ ọ ati gbogbo awọn enia rẹ ti ō fi silẹ fun igba diẹ Aṣẹ!!!

---

Si Oniwe Irohin Eko Akete.
L' Eko.

Ọgbẹni mi Ọwọn

*Erin ku Magudu fijẹ Ẹfọn ku Magudu fijẹ Magudu papa ku, ko r'ẹni jẹ on.*

Anu ṣeni pupọ lati ripe lati ọjọ gboro ti Ọgbẹni wa Professor Samuel Murray Harden (Ologbe) fi pa ipo da, a ko ri ẹniti yio sọ fun wa gẹgẹ bi igbesi aiye rẹ ti ri ati gẹgẹ bi o ti lo akoko rẹ lati igba ewe titi di ọjọ iku rẹ tabi ki a ri ẹnikan ti yio gbiyanju, ninu awọn isọngbe rẹ tabi awọn ti o pọwọ le e, lati bere idawo lọwọ ara Eko nitori ati fi ṣi aworan rẹ fun iranti awọn ọmọ wẹrẹ wa ti ko mọ iru Ogbogi iwe yi. Ẹnikẹni ti o ba ri kisa ti Professor Harden ṣe ni ile Afari Ogun l'Ẹhingbẹti, nijo ti a nṣi aṣọ lori aworan Ologbe Lọya Kirisi, laisi tabi tabi, yio pẹlu mi pe, ẹniti o tọ ki a ranti larin wa titi lai ni Professor Harden. Nitori eyi, mo bẹ gbogbo awọn alagba wa, papa awọn ti o mọ riri Ọgbẹni wa Professor Harden, ki wọn ki o pawọpọ lati ṣe nkankan ti yio wu ni lori nipasẹ ọrọ yi.

Mo dupẹ gidigidi lọwọ rẹ, Ọgbẹni Oniwe Irohin, fun aye ti o gba mi lati fi ọrọ yi sinu iwe irohin rẹ.

Emi ni tirẹ nitotọ,
OJULUMỌ.


ILE-ỌWỌ OYINBO ALALUMỌGAJI

# John Holt

NI ỌJA WỌNYI FUN TITA

Sarotu "Alasia"

Keke-ologere (Elerin)

Keke-Ologere (*Rudge Whit-Worth*)

Panu Iborule

Awo

Awo-abomafo

Eja-abomafo

Iyefun

Sulfuri

fuEn

Alum

Oda-dudu

Orisirisi Oda-ikunle

Iso

Panu-kiko'le

Isana (Atuko)

Ẹ bere ni Ṣabu JOHN HOLT ni Opopo-nla, ni Eko.

"*Ebani*" ni ede-waya ti ẹnikẹni le tẹ si wọn nibikibi ni Eko tabi ni Ilu miran ni *Nigeria*.

Si Oniwe Irohin, Eko Akete.

Mo juba o.

A dupẹ fun Ọlọrun to pese Alufa kan fun wa ni Ile-isin Ọlọrun (Church St: Peter) ni ijọ kẹtalelogun oṣu *March 1924*, ọrọ ti Bishop Oluwọle yan ninu Iwe Mimọ to fi ṣe iwasu ni eyi. Timoteu kini ori 4 ẹsẹ 12 ati ẹsẹ 16; Bishop sọ, pọnpọn ọrọ ninu iwasu rẹ, iwasu na dun to bẹgẹ bẹni-wipe ki Bishop ma pa ẹnu mọ, bẹ lori, emi papa ti mo gbọ iwasu na o dun mo mi pupọ bẹnipe emi ko gbọ iwasu Bishop Oluwọle ri, lẹhinna o wa sọrọ fun Alufa na papa iru ẹru ti Alufa ni lati ru ninu ijọ, o si tun sọ ti ijọ fun ijọ o si laye ijọ gẹgẹ bi a ti ṣe nfi Alufa si ori ijọ ati gẹgẹ bi ijọ ti ṣe le yan Alufa fun ara wọn.

Adura mi ni fun Alufa S. V. Latunde pe ki Ọlọrun ninu anu rẹ ki o ba gbe ẹru ṣọṣı na ka ale, ki o si fun ni ẹmi gigun ti anfani pẹlu. *Amin.*

Bishop si to gbogbo nkan fun ijọ ni ẹsẹsẹ o wa ku ohun kan pataki ti ani lati fi ye ijọ St: Peter gẹgẹ bi o ti yẹ ṣugbọn ijọ ko ṣe alaimọ eyi tẹlẹ, ohun na ni eyi, Bi akoko ati yan enia sinu iṣẹ ijọ, bi iriju ijọ (*People's Warden*) tabi iriju Alufa (*Minisier's Warden*) tabi akọwe *Parochial Committee, Secretary*, tabi awọn ti nyẹ owo ijọ wo (*Auditor*) ni ọdodun. O yẹ, o tọ ki a ma parọ wọn ni ọdọdun gẹgẹ bi Ijọ papa ti mọ, papa ẹnyin Ijọ ti ẹ nyan enia kanna ni ọdọdun, ẹ ro pe ko si enia to mọ iwe ni Ṣ ọṣi (*Church St. Peter*) mọ ni, ẹnyin na ẹ ro wo daradara bi iṣẹ ba gbe awọn enia ti ẹ nyan ni ọdọdun yi lọ si idalẹ nkọ? Njẹ iṣẹ Ọlọrun ko ni lọ tabi ko ni ṣe. ni *St. Peter* mọ kọ yẹn? Kamari, iṣẹ Ọlọrun yio ma lọ siwaju ati siwaju titi lailaị. Amin. Laifi ọta pe iṣẹ Rẹ nlọ.

Ki Ọlọrun ki o pẹlu Ijọ. ko jẹki anu Rẹ ko ya si ori Ijọ *St. Feter* ni ọdun yi aii titi lai. Amin.

Emi ni ti nyin nitotọ,

T'ENI-MA-SUNWONKI-GBO.

---

ỌJỌ GBOGBO BI ỌDUN.

***Olufunmi Store***

1, Kano Street, (Oyigbo Market) Ebute Mẹta, ṣi wabi-wọsi Akẹtẹ ati Bata obinrin, ati ni 106 *Broad Street*, niwaju Ojo *Barber*, ni iba jaba. Owo ọja ibẹ dinku.

## ẸBA KO ṢE Ṣ'ALEJO, GARI DI NAIN!!

Eko Akete ile ọgbọn.—Mo bẹrẹ f'oji o!! Ilu Eko yi a dun o!!! Odumare a to o!!! yio si gun perepere fun gbogbo wa, ati oni'le, ati alejo.

O nlọ si ọsẹ meje tabi ju bẹ lọ nisisiyi ti a ti bẹrẹ si ra panu gari kan ni nain (9d.)

Ṣāju akoko yi, sisi (6d) ni mo ranti pe awọn aya wa tabi bọyi (*Boy*) wa nra panu kan ṣugbọn kete ti a jẹ eyiti a ra ni Sisi tan ni mo gbọ pe panu gari kan di nain; o wa fi idaji (*50 per cent*) iye ti a ti nra panu kan ri le si.

Nigbati mo si bere idi ele (*increase*) yi, mo gburo pe nṣe ni awọn Onigari nru gari lọ si Igbereko Eko lọ ta ki ere (*Profit*) wọn ba le tun pọ si.

Bi o ba ṣepe otitọ ni ohun ti a gbọ yi, mo bẹ nyin, ẹnyin agbalagba olotọ diẹ toku, ki ẹ ba wa fi opin si aṣa bayi lọnakọna nitori ko si oko (*Farm*) ni igboro Eko, ti a le lọ hu gbaguda, lati ṣe gari. Ni gasikia kẹ, ọpọlọpọ enia ti o jẹ makunu ni ko si lowo *Joloff Rice* tabi *Tea* tabi *Coffee* lọwọ nigba-gbogbo ati pẹlu iwọnyi ko nyo ni bi munukun (gari) ti ma nṣe.

O yẹ ki a mọ pe "Amu ni Eko jasi," nitori olukuluku mọ daju pe oniruru ọna ni alejo ngba wọ ilu Eko. Nwọn a sa jẹun bi onile ko tilẹ yo kẹ.

Ki ẹnyin alagba ọlọla jọwọ ba wa feti si eyi ki ẹ si gba awa oṣiṣẹ silẹ lọwọ iyan ti awọn Onigari da silẹ yi. Awọn onigari na sa fẹ sọ Eko di "ko s'olori ni Aganyin, gbogbo wọn lo ngbe iga akan." Bi ko ba tilẹ ṣe aiye ni, mo ṣebi OLOWO Iga Idunganran ti kọ iru aṣa yi nigbakan ri. Lakoko ti ko si owo lode yi, ti alatẹ ko ta, oni Ṣabu ko ri onibārà (*Customer*) Gbangan Ẹjọ kun fun ẹjọ gbese, ni awọn onigari wa ro pe o tọsi lati ṣe ọkanjuwa fun ere ajẹju to ma njẹ ki apo owo jo danu nisalẹ. O ṣe!! Ẹ ro wo!!! Ranti pe "gbogbo wa ni yio lọ jihin fun Ḅaba," ṣe gafara fun mi fun ede Oyinbo yi:—

*Not an Act we do decays,*
*But every thought, word, an action will be seen in after days.*

Bi ọmọde ba nge igi ni gbo, agbalagba a mọ ibiti yio ṣubu si!! Eyiti o ku o di ọwọ nyin!!!

Tirẹ nitotọ ni,

AJALOLẸRU.

## EKO AKETE.

Eko, Saturday, April 26, 1924.

### ILẸ NṢU, ILẸ NMỌ, ỌLỌJỌ NKÃ A.

Ti a ba ri oṣu mẹrin si ni yio di ọdun karun ti Gomina wa Sir Hugh Clifford oloye nla G.CM.G., ti de ibi lati wa "jọba" lori wa; a niran ọjọ ti on ati aya rẹ Awẹlẹwà Ọlọrunsẹgi de si'lẹ yi; gẹgẹbi ojo ti nfun wẹnnẹn-wẹnnẹn ni ọsan ọjọ na—*Friday* ọjọ kẹjọ oṣu *August 1919*—Ẹnyin ara wa yio tun niran pe ko l'ọjọ ko l'oṣu ti o de bayi ni ijangban akọkọ ba Olori wa ni Iga Idunganran, ṣugbọn ti ina rẹ ko ran pupọ ki a to fi pa; ninu ọdun to tẹle ọdun na ẹwẹ, a ni ọdun 1920 ni a tun ri oriṣiriṣi idanwo miran ti o tun de ni ọna ti ẹnikẹni ko la ala si, nipasẹ gba were ng ko gba were, ti o si d'ogun ti o d'ọdẹ titi di oni oloni! ãjọ wo ni ilu ko ṣe tan lati rọ Gomina ninu pe ki o fi ẹṣẹ ekeji yi ṣe "Kẹbẹ," ṣugbọn ti ọrọ na si di ẹti; gẹgẹbi o si ti jẹ pe boya Gomina le fi iṣẹ apa tiwa ni ilu *Nigeria* nibi si'ẹ lọdunni, tabi lọdun kan-abọ si, ko si ore meji ti o le ṣe ilu Eko bi ore iranti lailai, ju pe ki o gbe Eleko si ipo rẹ pada lọ. Olubori ore ni eyi yio jẹ fun wa bi Gomina ba le ṣeyi fun ilu, ki o si d'oju ti ẹlẹgan. Ẹnyin ara, ẹ wõ na, ta lo le mọ pe o ti nto ọdun karun niyẹn ti ọrẹ wa nla yi ti de si igboro ilẹ yi; ati pe o si nlọ si ọdun kẹrin nisinsinyi ti rogbodiyan yi ti de ba Eleko Ọba wa? Nitotọ ako o ati igba ko duro de ẹnikẹni; ilu ki kere ki o ma ni atan. Adura wa ni pe ki Baba ma ṣai pa sã yi da si ti anfani fun olukuluku, tcbẹ ti ọrọ Eleko yi yio fi yanju rekete nikẹhin, ti gbogbo wa yio si fi ṣe itan pa.

### IRANTI.

Ashimawu Ayinkẹ tẹrigbaṣọ ni 18 Ita Balogun lọjọ 9 oṣu yi; o jẹ kiro-kifọ aya Joseph Olukun. Ki Baba f'ọrun kẹ ẹ.

Si Oni'we-irohin "EKO AKETE"

Mo juba o,

O jẹ ohun iyanu fun mi lati ka ninu *Eleti Ọfẹ* ti ọjọ 16 oṣu yi nipa aworan Jesu Kristi ti Olotọ Aja kan sọ di iṣẹ pataki ti o si nfẹ fihan pe Onigbagbọ fau-fau ni on iṣe. Ẹnikẹni mọ dajudaju pe awọn Ijọba (*Town Council Authority*) ti kan nipa fun awọn aṣere *Cinema* lati ma fi aworan (*Films*) wọn han ṣiwaju ati fihan fun awọn to ba wa woran. Njẹ bi eyi ba ribẹ, kini aroye ọtẹ to ba Olotọ Aja (baba alanu) ko daju pe Olotọ Aja ronu jinlẹ ki o to ma bẹbẹ lọdọ awọn Alufa *C. M. S.* ati ti Wẹslẹn nitoripe Archdeacon T. A. J. Ogbunbiyi papa ti nṣe aworan Jesu Kristi ni ọna arabara ni Ebute Ero, papa Alufa Ijọ Wẹslẹn kan si tun ṣe irufẹ rẹ (*Magic Lantern*) lati fihan awọn ero ijọ rẹ (*Members*) irufẹ iya ti Jesu Kristi jẹ lori agbelebu. Boya Olotọ Aja ko mu ọkan anu lọ wo *Cinema* ninu ọsẹ ikanu yi lo jẹ ki o ma sọ ọro bayi; kini Olotọ Aja nfẹ ki awon *C.M.S.* ati Wẹslẹm ṣe si irufẹ ẹbẹ agabagebe yi? Nko ni igbagbọ si pe Olotọ Aja nfẹ fihan pe ikanu Jesu lo mu on lọkan pupọ bikoṣe airikanṣekan. Olotọ Aja ko mọ pe owo ni awọn oni *Cinema* fi nra awọn aworan oniruru wọnyi tabi inu rẹ ndun si awọn aworan ti Ijọba daduro nipa ti rogbodiyan ologbe Delphonso, pataki ewo lo jẹ ere ninu nkan wọnyi to di Iyọ to bo o tobẹ to fi tun nbẹbẹ ati da awọn aworan bi ti Jesu Kristi duro. Ohun kan da ni loju pe awọn *C.M.S.* ati Wẹslẹm, nronu jinlẹ, wọn ko dabi Olotọ Aja afẹnu jẹ onigbagbọ enia, ẹniti ki ro rere si ọmọ ẹnikeji rẹ. Njẹ bi onigbagbọ mo fi ọrọ Bibeli Mimọ yi gba Olotọ Aja niyanju. :—

"Gbogbo nkan wọnyi ni ẹnyin nṣe ti awa mọ, ti awa si dakẹ, ṣugbọn bi ẹ ba bere a o ma ka wọn lẹsẹsẹ.

Emi ni tinyin nitotọ,

Fitila Ọba.


## AGA, AGA, AGA

FUN YIYA NI ILUPESI, ẸNUỌWA, LI EKO.

OWO PỌKU NI A FI NYA NI NISISIYI, (1½d.) KỌBỌ KAN PẸLU ABỌ.

Lọ si ọdọ Alabojuto,

Ọgbẹni J. A. OSHODI,

No. 26, Ita Ọbun-Eko,

LI EKO.

# FUN WA NI ONJẸ OJỌ WA LONI.

[ *Lati ọwọ* ATARI AJANAKU. ]

Si Oni 'we-irohin "EKO AKETE."

Mo bẹrẹ f'oji !

Adura ti a ṣe si oke wosika yi—adura pataki ni, nitori oriṣa bi ifun ko si, ojojumọ lo ngba onjẹ.

Lẹhin ti Jesu ti kọ ni pe ki a juba Baba wa to nbẹ l'ọrun, ohun ti o tun kọ ni ṣikeji ni lati tọrọ onjẹ ojọ wa lọwọ Rẹ ; ki a to wa bẹbẹ pe ki O maṣe fa wa sinu idanwo ọmọ araiye ati Bilisi Aṣitani.

Olowo njẹun, talaka njẹun, ṣugbọn onjẹ ẹnikan yatọ si ti ẹnikeji : ọpọlọpọ enia nisisiyi ni ati jẹun di ẹti si lọrun. Kilo mu eyi wa, o ha ṣe pe nwọn ko ngbadura lati torọ onjẹ ojọ wọn lojojumọ ni ? Agbẹdọ ! Njẹ bi nwọn ba ngbadura, iha ṣe pe Ọlọrun ko f'eti si ohun ẹbẹ wọn ni ? Agbẹdọ !!

Ṣugbọn adura laisi iṣẹ, pabo ni ; owo ti ẹlomiran iba si fi jẹun sinu ara rẹ, tẹtẹ lo ma fi ta tan, ẹlomiran nna tirẹ sidi ọtẹ, ẹlomiran yio fi tirẹ mu ọti, ẹlomiran, Kōto lo ma na tirẹ si tan nibiti o gbe ndu ogún ti ko tọ si i lati jẹ ; ninu egbogi awure ati ògun Madarikan ni ẹlomiran ndi alakisa si patapata. Oniruru inakuna bayi lo nsọ enia pupọ di ẹdun arinlẹ lode Eko A ko sọ ti awọn ti ebi npa nitotọ, ti wọn si nwa iṣẹ ṣe loju mejeji, ti nwọn ko ri, tabi ti awọn alatako di lọna ijẹ ti ko si ri owo fi gbọ bukata rẹ mọ. Anu irufẹ awọn enia bẹ ṣe wa pupọ ; adura wa si ni pe ki Ọlọrun ma ṣai pese iṣẹ anfani fun wọn, ki O ma si ṣe jẹ ki ebi mu pa wọn ku.

Ṣugbọn ẹniti o nna owo rẹ ni inakuna, ati ẹniti ko tilẹ ri iṣẹ ṣe rara nkan kọ ni ati jẹun ṣoro fun nisisiyi. O ṣoro fun ọṣiṣẹ, Akọwe, Oniṣowo, ati bọkini pupọ la i jẹun yo fun ara rẹ tan, ki o si bọ gbogbo awọn ara ile rẹ ni abọyọ. Kilo mu inira yi wa ? Iyan ! Iyan !! (*Famine*) mu lode. Gari di nain (*nine pence*), ẹba ko ṣe ṣe alejo mọ.

Nitotọ, gbogbo nkan ni owo rẹ ga nisisiyi ju ti atijọ lọ, ṣugbọn bi a ti le ṣai ra nkan miran ti owo rẹ ga pupọ ju, a ko gbodọ ma ra onjẹ. Bi ẹwu kan faya a le gbe fun Telọ (*Tailor*) fun atunṣe, bi bata gbọ, a le gbe e fun Ṣumẹkà (*Shoemaker*) ko sọ di ọtun ; ṣugbọn bi ọbẹ tan ninu iṣasun, ti gāri tan ninu apo, ọgbọn wo ni ẹnikẹni le da si ju wipe ki o towo bọ apo—apo tirẹ papa ni o, ko nṣe àjùfu ti ẹlomiran bi ọmọ Jaguda.

Iwe-irohin kan tabi meji sọ fun wa ni lọlọ yi, idi rẹ ti gāri ati ohun jijẹ miran fi wọn gogo bayi, ti mo ba si ranti daradara, nwon gba Ijọba ni imọran wipe ki o da awọn ti o nko gari lọ ṣowo ni Cameroon, Port-Harcourt ati ibomiran duro.

Boya ti Ijoba ba ṣe bẹ nitotọ, nkan le r'oju diẹ ; yio tilẹ rọju, tabi-tabi ko si ninu eyini. Ṣugbọn awọn talo njẹ gāri pataki ni Port-Harcourt, Secondee ati Cameroon, bikoṣe awọn enia wa kanna ti o ti ilẹ yi lọ ṣowo nibẹ. Awọn ara ilu ibẹ papa, ọgẹdẹ ati koko ni nwọn njẹ ju.

Nitotọ, bi ohun jijẹ ba wọn ni Ilu-oke, lọgan ni Ọba ibẹ yio paṣẹ wipe ẹnikẹni ko gbọdọ mu nkan jijẹ kuro ni ilu lati lọ fi ṣowo ni idalẹ titi onjẹ yio fi pọ ni ilu si i, ṣugbọn eyi yio jẹ ohun-ọgbin ilu na papa—ko nṣe eyiti a ko lati ilu miran lọ sibẹ.

Ara Eko pupọ lo ni oko nlanla ni Agege, Ijọko, Alagbado, Oṣodi ati ibomiran pẹlu, ṣugbọn dipo eyiti nwọn iba gbin gbaguda, iṣu, agbado, ọpẹ, ata, iru, ẹfọ ati ohun jijẹ miran sibẹ janrẹrẹ, Cocoa ati Obi lo gba gbogbo oko kan, bẹni ṣaṣa ni ara Eko to le jẹ *chocolate* ti a fi Cocoa se ni alejo, nwọn ko si mọ obi jẹ pẹlu—ṣugbọn sibẹsibẹ, bi Oyinbo ba ti ri cocoa ra, ti Hausa si nri obi ra, o tẹ awọn agbẹ Eko lọrun. Gari ti awọn papa pẹlu ọmọ wọn njẹ ko si fun tita, elubọ ko si fun tita pẹlu.

Awọn Ijẹbu Ejinrin, ti Ikorodu, ti Emina, ti Ẹpẹ ati awọn Awori diẹ ṣa lo ni lati ma rin gari fun ara Eko jẹ, ki ara Ọjọ ati Badagry ma ta epo fun wọn jẹ, ki ara Jẹbba ma ta iṣu fun wọn, ki ara Bode Sadu ma ta Elubọ fun wọn, ki Hausa ma ta alubọsa ati ororo-ẹpa fun wọn, ki awọn ara Eko papa sa ma ta cocoa pẹlu obi lẹhin ti nwọn ba ti jẹ gāri Ijẹbu yo tan bambam.

Obinrin tabi ọdọmọbinrin Eko melo lo mo Gbaguda lati rin ka ma ṣẹṣẹ wipe ki o yan Gari, ọmọ Eko melo lo ha le sọ Iṣu di Elubọ tabi Igbado di Ẹkọ—beni pataki onjẹ wa ni nwọnyi. O san pupọ larin Imale, ṣugbọn awọn ọmọbinrin Kiriyo fẹ ṣe iṣe akọwe Ọba. *They have left undone those things which they ought to have done and are doing those things which they ought not to have done and there is no health in them.*

Bi awọn Agbẹ (*Farmers*) Eko ko ba tete bẹrẹ si gbin Gbaguda daradara nisisiyi, ki awọn obinrin wa, t'ọmọde t'agba, ki awọn alaṣọ-riro ati oniyẹri, si bẹrẹsi kọ bi a ti nṣe Gari, to ba jẹ pe ori Cocoa ati Obi ati ikilọ pe a ko gbọdọ ko Gari lọ si *Port Harcourt* ati *Secondee* mo nkan ni o joko si ni, ki ẹnu maṣe ya wa bi Gari ba tubọ di "golu," ṣugbọn a ko gbadura ko ri bẹ rara.

Ko si ohun itiju kan ninu Gari ṣiṣe tabi tita ; ọkanlawon onjẹ ni Gari jẹ. A nṣu ṣù, a nrō rò, a nwa wà, a ntẹ tẹ.

Lakotan, a bẹ gbogbo ẹniti o nta Gari ni Idumagbo, ni Ọbalende, ni Ebute Ero, Oyigbo, ni Ita Faji, Ereko, Ararọmi ati ni adugbo miran kiri, ki nwọn jọwọ din owo ti nwọn nta a nisisiyi ku nitori awọn mẹkunnu ilu, nitori awọn ópo ati nitori awọn ọmọ alainibaba.

Emi ni tinyin nitotọ,

## ALAS, MY SISTER !!!

It is with the deepest regret we chronicle the sorrowful news of the death of Mrs Layinka Agbebi *(nee Wright)* wife of Mr. G. Debayo Agbebi C.E. of *Folamobi House* Igbosere Street, which occured on Thursday the 24th instant at their residence.

To say that her passing-away came to the community like a bolt from the blues is to give expression to poverty of language for she was not known to be so seriously laid up as to warrant so sudden an end; even those who chanced to see her and her husband with their little one on their return from service on last Good Friday confirmed this view.

The funeral which took place yestermorning at Christ Church Pro-Cathedral was attended by quite an overflowing sorrowing crowd which testified in a high measure to the esteem in which she was held.

As we write with trembling hand, these lines by Mrs. Mary Hemans came to our recollection to show what shadow are we, and what shadow we pursue whilst in this vale of tears.

"Leaves have their time to fall,
And flowers to wither by the North wind's breath
And Stars to set.
But Oh! Thou hast all seasons for thine own,
O Death"

Our condolence to the stricken husband and the bereaved families.

She shall rise Again!!!

## CITIZENS' WISHES SATISFIED.

I am almost more than satisfied to learn that the District Officer of Ikorodu Mr. E. K. Milburn has despersed the two irresponsible sets of hooligans styling themselves "Bunukonu and Zunguru Societies" at Ikorodu.

These Societies had as their object the pernicious aim of causing some unrest in the town.

To strengthen this order, I would suggest that the Deputy Registrar and the Police be requested to issue no pass to these hooligans; as their expedition of abuses and vilification is not only vexatious to the citizens but is in contravention of the British Law and Principle.

It is also advisable that the members of these obnoxious Societies be informed that a disregard of the injunction will result in their being severely punished or deported. We desire order, peace and tranquility in the town not hooliganism.

Some men not conversant with the state of affairs, may be of opinion that the suggestion of deportation is too drastic a measure for the offence, to such men. I may reply that imprisonment is of no consequence to these pests.

It would indeed be a matter for profound astonishment if their "infallible" president at the Secretariat should fail to cite a law or get one invented in their favour.

I need add that this President is useless to his Christian companions, to his country, his race and almost to himself.

Heaps of cheers and thousand applauses to Mr. E. K. Milburn fo[illegible] laudable action. Hurrah.

Mr. Editor for the space allowed,

JOS. M. SHONUBI,
*on behalf of the Citizens.*

## PAGIDARI! ONIṢEGUN TITUN NIYI.

Ẹ ha ti ri *Native Doctor* S. Bankọle Abẹruagba Mafarapa ri? Bere rẹ ni 23, Pedro Street, Oko Awo, ati ni 1, Forsythe Street, Lafiaji. Wa fun gbogbo arunkarun ti o ba mba ọ ja a o si ṣo diẹ fun ọ.

*Epilepsye*—Warapa | *Madness*—Were
*Small Pox*—Ṣọnpọnọ | *Leprosy*—Ẹtẹ
*Ulcer*—Egbo | *Rheumatism*—Lakuregbe
*Bronchitis*—Ikọ aiperi | *Elephantiasis*—Jakutẹ
*Dysentery*—Igbẹ ẹjẹ, Ọrin
*Dermatities*—Ekuru, Ifan
*Malaria Fever*—Arun Iba
*Pneumonia*—Igbonọ, Ikọ.

Bi obinrin rẹ ko ba tete ni oyun, mu wa.
Bi obinrin rẹ ba ni oyun ki o le bi pẹlu irọrun mu wa.
Bi obinrin rẹ ba nbi abiku mu wa.
Bi aran ba mba obinrin rẹ ja mu wa.
Bi aisan amodi ba mba ẹnikẹni ja ki o wa.
Bi obinrin rẹ ko ba ri nkan oṣu rẹ, mu wa.
Bi Ẹda ba mba obinrin rẹ ja, mu wa.
Bi arun aṣiri ba mba iwọ papa ja wa.

## NOTICE.

IN THE MATTER OF THE ESTATE OF
LONGE ADELAKUN
(Deceased)

*Pursuant to the Statute 22nd and 23rd Victoria Chapter 35 intituled "An Act to further amend the law of property and to relieve Trustees*

Notice is hereby given that all Creditors and other persons having any debts claims or demands upon or against the estate of LONGE ADELAKUN late of 9, Strachan Lane Lafiaji in the Town of Lagos in the Colony of Nigeria who died in Lagos aforesaid on the 27th day of June 1923 intestate and administration of whose personal estate and effects was granted to KADIRI AYENI ADELAKUN of 9, Strachan Lane, Lafiaji, Lagos aforesaid by the Supreme Court of Nigeria on the 24th day of March 1924, are hereby required to send in particulars in writing of their debts claims or demands to me the undersigned Solicitor to the Administrator at my Office at 4, Oil Mill Street in Lagos aforesaid on or before the 31st day of May 1924 and Notice is hereby further given that at the expiration of which time the Administrator will proceed to pay and distribute the assets of the said deceased amongst the persons entitled thereto having regards only to the claims and demands of which the said Administrator shall then have had notice and the said Administrator will not be liable for the assets of the said deceased or any part thereof so distributed to any person or persons of whose claim or demand he shall then not have had notice.

And all persons indebted to the said estate are hereby required to make immediate payment of their indebtedness.

Dated this 10th day of April, 1924.

S. H. A. BAPTIST,
*Solicitor to the Administrator*

### Si Oni'we-irohin "EKO AKETE."

Jọwọ gba mi ni aye rebete ninu Iwe-irohin rẹ, lati sọ ọrọ diẹ lori ọrọ ti Oni'we-irohin *Spectator* fi ẹnu ba ṣoki ninu Iwe-irohin rẹ ti ọsẹ kẹrin sẹhin (15/3/34) nipa ti ede-ko-yede ti o wa larin Ijọ Yaba (*Wesley*) ati olutọju (*Catechist*) Ijọ na.

Nigbati mo ri iwe na ka, ohun ti o gun mi lọkan ṣinṣin ni pe ile-ẹkọ (*School*) eyiti o ti wa ni Yaba lailai bi aṣọ inu igba, ti a parẹ kuro lai ni idi pataki kan, ni akoko olutọju Ijọ yi.

Olukuluku ni o sa ndu pe ni ibikibi ati ni ipokipo ti Ọlọrun ba gbe on si, ki a le ma da orukọ akoko na ni rere, ki a si le ma gbadura fun on pẹlu.

Ọran ẹkọ ki iṣe ọrọ ti a le ma fi ṣe ọrọ ẹrin rara, papa ni akoko yi; ẹkun rẹ npa ọpọlọpọ orilẹ-ede loni, ohun ẹdun gidigidi si ni fun mi lati gbọ pe nitosi Eko yi, a ṣi le ri sibẹ wipe a nti ilẹkun ile ẹkọ mọ awọn ọmọde, papa nibiti o jẹ wipe ko tun si ile ẹkọ miran ni itosi.

Mo gbọ wipe kaka ki olutọju Ijọ yi, nipa iyọnu ti awọn Ijọ rẹ nṣe, wa ọna lati tun ṣi ilẹkun ile-ẹkọ na, agunla ni o nda lojojumọ, o si nwipe "Ohun ti a ti kọ, a ti kọ na."

Eyi ko buru, ṣe igba ni Ọba ni ko sa ni aiye. Ijaiya ti Kẹkẹ (*Motor*) ti o pọ lode ko fi ọkan ọpọlọpọ obi balẹ lati ran awọn ọmọ wọn lọ si ọna ti o jin—bayi ni a le ri pe ohun ti awọn enia na iba na ọwọ mu ni para, olutọju Ijọ na fi ranṣẹ si ipara fun wọn; eyi ko ha to lati mu irẹwẹsi ba ọkan enia bi?

"Gba were, nko gba were, ni ọja fi npariwo" owe ni o. Gẹgẹ bi mo ti gbọ, awọn ara Ijọ na fi iwe ẹsun ranṣẹ si iya Ijọ (Olowogbowo) laipẹ yi, ki iṣe lori ọrọ ti ile-ẹkọ ti a ti yi, ṣugbọn lori ẹṣẹ mejila miran lọtọ gede, ti ko yẹ onisẹ Ọlọrun, ti a si sọ pe a ti nṣe kilọkilọ rẹ fun u ṣugbọn o jingiri, ati pe nigbati a pe e pe ki o wa sọ eyiti o ri si iwe ẹsun na, ko le jiyan si ọkan ninu ẹsun mejila na pe ki iṣe iwa on. Pẹlupẹlu eyi ki iṣe igba ẹkẹta mọ ti a gbọ pe awọn ara Ijọ na ti nparapọ fi ẹjọ rẹ sun iya Ijọ (Olowogbowo) pe wọn ko fẹ gẹgẹ bi olutọju wọn mọ, ki nwọn sa parọ rẹ fun wọn, ṣugbọn ti a nbun wọn ni suru.

Mo gbọ pe aini itara ati aibikita fun ilọsiwaju iṣẹ jẹ ọkan ati kekere ninu ẹsun ti a fi sun. Nko da ẹjọ, ṣugbọn bi o ba gba pe otitọ ni awọn ẹsun mejila yi, ko si iyemeji lati gbagbọ pe bi a ti ṣe ti ilẹkun ile-iwe na ko ṣẹhin rẹ.

Dajudaju awọn Ijọ rẹ ko le fi danyin-danyin ẹran iṣẹ rẹ, papa awọn ọdọmọkunrin ti o mọ fohun ti o yẹ, ati bi nwọn ti nṣe ni ijọ miran Mo gbọ pe alayan papa ni nwọn jẹ, ati pe nwọn si mura lati na-owo, na-ara, fun iṣẹ Baba wọn oke, nwọn si kọ ki a ma pe wọn ni "Aguntan ko pa aṣọ ẹṣi da."

Ọgọ-tà, ọgọ-ọ-tà, owo alaru a pe ko wọ fun iṣẹ Ọlọrun. Orişirişi Alufa ni o sa wa ni aiye wa isisiyi, ki Olodumare jọwọ ki o ma jẹ ki a pade Alufa bi ti Eli ninu Ijọ-kijọ ti a ba wa, Alufa ti yio ma wipe eyi-keyi ti ẹ ba ṣe si'pa ile Ọlọrun, o dara o, ko dara o gẹgẹ mi lo ṣe; eyi ni Alufa Eli wi ni ọjọ wọnni, ti Oluwa fi binu si, ti on pẹlu ọmọ rẹ fi ku ni ọjọ kan ṣoṣo; ki Oluwa ma jẹ ki a ri o. Amin.

Ki iṣe ninu ọrọ didun lori igi iwasu (*Pulpit*) nikan ni ọna lati ṣe iṣẹ, a sa ri ka ninu iwe mimọ pe bi enia tilẹ nfi ohùn enia ati ti Angẹli sọrọ ti ko si ni ifẹ, o dabi ohun elo idẹ lasan ti ndun, a si tun ri ka pe, igbagbọ lai si iṣẹ, oku igbagbọ ni.

Akoko wa fun ohun gbogbo; a ko le mu aṣọ ogbologbo ti ko ba ode mu, ki a ran mọ aṣọ titun daradara (damasi) bi ko ti si ọmọge ti o jẹ mu lọ si ode, bẹni ko si Ijọ Ọlọrun ti ina rẹ le dun lati gba Alufa ti o yarọ, tabi ti ko mọ irufẹ ohun ti o dara ti o si ba ode mu.

O dun mọ mi pupọ lati gbọ pe sibẹsibẹ bi olutọju Ijọ wọn ko ti ṣe iṣẹ rere larin wọn, wọn ṣi ni ọkan onigbagbọ si, wọn ko fẹ ki a gba ẹnu ijẹ lọwọ rẹ, ṣugbọn nwọn nbẹbẹ pe ki a sa ṣe iparọ rẹ fun ẹlomiran ti yio to iṣẹ ṣe bi nwọn ti nfẹ, ti yio si jẹ akikanju oluṣọ-agbo, ti yio ma kigbe nigbati Koriko tabi Kiniun ba nbọ.

Ẹnyin agba-agba, ẹ lọ tun Ijọ nyin ṣe, ẹ maṣe jẹki o fọ. Ina ku f'eru boju, Ọgẹde ku fi ọmọ rẹ rọpo ni awọn ara atijọ ma npa ni owe, bi ẹ ba gbe awọn ọdọmọkunrin nyin ni igbọnwọ soke, ọwọ gbogbo nyin yio to ohun ti ẹ nnaga fun.

Mo wa lẹhin Oni'we-irohin *Spectator* ti o da ni imọran pe bikoşe pe Alufa S. A. Pearce, ati Onişegun Orişadipẹ Ọbasa, pẹlu Alufa agba ba pa ọwọ pọ yi okuta idigbolu yi kuro lọna, kẹkẹ iṣẹ ijọ na ko le lọ siwaju, kaka bẹ, yio ma pada si ẹhin.

Otan lẹ'nu nisisiyi, ṣugbọn o ku ni ikun.

Mo dupẹ lọwọ rẹ, fun aiye ti o gba mi.

Emi ni,

ABEDNIGO.

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

ROMAN CATHOLIC. (HOLY CROSS)

Masses will be sung by Priests appointed. Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi. (MORNING)

Masses Isin Arọ,

6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

(EVENING.)

Masses (Benediction) Isin Ibukun.

4.45—5.30 6.45—7.30.

ST. MICHAEL'S (Lafiaji.)

MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.
EVENNING. 5.45—6.30 p.m.

ANGLICAN

| Time. | | Preacher. |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Christ Church. | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. Paul's (Breadfruit) | Rev. H. Ogunro |
| 6.30 p.m. | do. | Rev. C. A. Ṣowunmi |
| 9 a.m. | St. John's (Aroloya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. Peter's (Alapako) | Rev. S. V. Latunde |
| 6.30 p.m. | | do. |
| 9 a.m. | Holy Trinity (Ebute-Ero) | Rev. A. N. Cole |
| 6.30 p.m. | do. | Rev. S. J. Gansallo |
| 9 a.m. | St. David's (Jordan) | Rev. J. A. Leigh |
| 6.30 p.m. | do. | do. |

WESLEYAN

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Tinubu | |
| 7 p.m. | do. | |
| 10.30 a.m. | Ereko | |
| 7 p.m. | do. | |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | Rev. D. A. Bababunmi |
| 7 p.m. | do. | Rev. S. A. Pearce |
| 10.30 a.m. | Ọbun Eko | do. |
| 7 p.m. | do | Bro. E. A. Oluwa |

AFRICAN (COMMUNION)

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Jehovah Shalom | Rev. G. A. Oke |
| 7 p.m. | do. | Rev. J. F. Ogunko |
| 9 a.m. | Erelu | Bro. J. H. Lawson |
| 7 p.m. | do. | Bro. Ignatius Martins |
| 9 a.m. | Christ Church (Ebute Mẹta) | Bro. T. D. Shaw |
| 6.30 p.m. | do | Rev. G. A. Oke |
| 9 a.m. | Bethel | Rev. E. A. Akinọla |
| 6.30 p.m | do | do |
| 6 a.m. | Zion | Rev. N. J. D. Ṣomuji. |
| 6.30 p.m. | | do. |
| 10.30 a.m. | African Methodist | Bro. E. A. Williams |
| 4.30 p.m. | do. | Bro. T. J. Ade Green |

FIRST BAPTIST CHURCH

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | | Bro. J. A. John |
| 6 30 p.m. | do. | Rev. J. R. Williams |

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Araromi (Baptist) | Bro. J. F. Oshodi |
| 6 p.m. | | Bro. John Apena |

EBENEZER (BAPTIST)

| | |
|---|---|
| 9 a.m. | Rev. A. A. Puddicombe |
| 6.30 p.m. | Bro. Joseph Bandele |

BROTHERHOOD

| | |
|---|---|
| 7.30 a.m. | Pastor A. Adedeji Iṣọla |
| 7 p.m. | do. |

St. STEPHEN'S (EPETEDO)

9 a.m. & 4 p.m. Very Rev. J. G. Campbell

AHMADIA (ISLAM.)

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹinde
5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajọṣẹ (Bamgboṣe Street.)

ZION CONGREGATIONAL.

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Kakawa St. | Locum Tenens. |
| 4 p.m. | do. | do. |

SALVATION ARMY.

10 a.m. Glover Memorial Hall Major E. E. & Mrs. Grimes
7 p.m. do. do.

CHURCH OF GOD

10 a.m. 22 Ọdunlami Street, Breaking Bread
7.30 p.m Open Air Service at Campbell Square, Edwin Mathew & Wm. C. T. Terrell

---

## IGBẸ L' OWO WÀ.

Bi awọn Oyinbo Oniṣowo ilẹ yi ti gba awọn Ọja wọnyi si l'ọsẹ yi ni eyi:—

EKURỌ

£13 10 0—£14 fun *ton* kan.

EPO.

£24—£24 10 0 fun *ton* kan.

COCOA.

£16 10 0—£18 10 fun *ton* kan.

---

KANO.

ẸPA.

£12 0 0 fun *ton* kọkan.

AWỌ (*Skins and Hides.*)

Skins 1/9d fun lb kọkan.
Hides 5d fun lb kọkan.




# ERVEN LUCAS BOLS

## AMSTERDAM

***1575***

---

Whenever you see the word Bols it means a reputation of over 300 years.

***Bols very old LIQUEUR GIN is the Gin for the man of good taste.***

## STONE JARS AND GLASS JARS

**5s.** per Bottle

***FROM***

# GRACE BROS.

***— DRINK IT NEAT. —***

# R. S. JAMESON,

## Licensed Auctioneer & Appraiser,

Broad Street, LAGOS.

---

***Prompt, reliable and intelligent Service.***

---

Property real and personal sold and valuations made for Probate.

---

Low rates of Commission and immediate settlements.

## H. S. Freeman

(Photographer-in-Chief to His Excellency the Governor of Nigeria.)

Dealer in all kinds of Photographic Materials

**Films, Post Cards, Views etc.; etc, on hand.**

"Also films undertaken for development"

Satisfaction Guaranteed.

*Office* :—106, TOKUNBỌ STREET, LAGOS.

*Telegraphic address* :—"**FREEDE**" LAGOS.

P.O. Box 495.



## ILE OWO KADUNA

to mbẹ lẹgbẹ Ile-afin Ọgbẹni A. W. Thomas ni 75 ati 81, Ita Odunfa, (Anikantamọ) L'Eko.

Awa ni orişirişi Kẹkẹ-ologere ati Kẹkẹ pupu-pupu ni tita, a si ni awọn "Ero-ija" wọn pẹlu.

Lati ọdun 1921 l' a ti wa lẹnu işẹ yi, awọn ọja wa si to ọja o ni igba pọun (£200.) Ko si bi Kẹkẹ-ologere kan tabi pupu-pupu kan ti le bajẹ to ki a ma be'ro: a si nra awọn "oku" Kẹkẹ-logere, oni-pupu-pupu, ati Ẹrọ-akọrin (*Gramophone*) ti a ntun şe ti a si tun nta owo pọ̃, bi £3, £4, £6 10 fun awọn iti ko ba to pẹmu olowo-nla ru.

Ẹ wa tabi ẹ kọwe şọwọ si Olotu Ile-owo i:—Ọgbẹni SAM ADE CLAY ni adugbo daruko loke yi, tabi ni No. 1, Ita Macaulay (Okepopo) l'Eko. Owo lọwọ gbogbo Ọja rẹ o, aibamọ.



## AIYELẸSỌ ỌLARINDE

Repairer of all kinds of Bicycles, Gramaphones, Fitting and Sewing Machines.

*Workshop* :—20, WILLIAMS STREET, LAGOS.

*Residence* :—135, IGBOSERE ROAD,

**Charges Moderate.**






*4/6 each.*

## The Kaduna Store,

75 & 81, ODUNFA STREET,

*near Mr. A. W. Thomas's palatial residence.*

ẸBUN HOUSE, LAGOS.

begs to inform all Cyclists and Motorists to buy always at our Store, complete spare parts and accessories for all makes of Motors, Bicycles, etc

Established 1921, we have much pleasure to say that we have added to our STORE, Goods to the tune of £200, being expert in the repairs of Motor-cars, Bicycles and all other machinery. We specialise in the purchase of old Cars, Bicycles, Gramophones which are minutely repaired by us and in turn, sold to those unable to afford high price, at giving-away prices, viz:—£3 £4 £6 10s. respectively, according to durability and taste.

For particulars, apply to the Proprietor :—

SAM ADE: CLAY of the above address, or at 1, Macaulay Street, Lagos.

TERMS :—Cash with Orders.



## The Nigeria Commercial Training Institute.

ESTABLISHED JANUARY 1924.

The above Institute offers students an opportunity to undertake its Training in Short-hand, Typewriting and Civil Service English.

Further particulars can be obtained on application to :—

J. OLOYEDE DAVIES,
*Principal and Proprietor*
10, Upper Offin Lane,
Lagos, Nigeria.

TERMS :—
Absolute satisfaction with results, or money refunded.

# A. KESSLER,

7, Labinjọ Lane. Williams Street.
*P.O. Box 459.*
SAMPLE SHOW ROOM.
Samples of all wanted goods exhibited.
*Agent for* ARNOLD SCHLESINGER,
Hamburg, Germany.









**Sale of**

Hand and Foot Sewing Machines "Alder" and "Mundlos," Pilsener Beer, "Lion" Brand per case 31/-, Champagne per case 24/2, £3. 5. 0.

Earthenware, Carpets, Berlin Wool, Lamps, Clay Pipes, Kitchen Clocks, Euergon Medicine, Fez Caps, Cycles Lady's and Gent's, Stoves

*Orders for any kinds of goods find quickest execution.*

**For general information :**

A new lot of Sewing Machines has arrived with last Steamer. For Sale: I have further Records, Campbeds, Indescendant High Power Lamps at special cheap prices.

*A visit to my Show Room will give you satisfaction.*

# JACOB AJAYI,

*General Woollen Trader,*

has on hand Woollens in endless variety at 50, Dosunmu Street, Lagos, at

**Prices to suit everybody.**

*Call now, fortune awaits you.*

## Aworan Alarabara.

A ni Aworan oniruru fun tita lati fi ṣe ile li ọṣọ. A ni ti titẹ oku Jọṣu, ti igbati a da a li ẹbi iku, ti Onjẹ-alẹ ikẹhin. A ni ti Adam ati Efa, ti iṣẹdalẹ aiye, ti Nebuchadenezar nigbati o wa ninu ola rẹ, ati nigbati o di ẹranko; ti obirin ti o fi, ọwọ mu ejo, ati ti Ọba Tatambulu.

A ni ewe Taba fun kika ta, Ọṣẹ Olọwọ—agaga; Iyọ-iyọ mbẹ lọwọ wa fun tita bi wọbu, bi o ba fẹ ẹ ni *lọnu* a le ta a fun o, Iṣana Alapoti fun tita, ko si bi a ti nṣe wọn. Oriṣiriṣi ọja lo wa lọwọ wa, iwọ ko le ba wa ṣowo ko ma jere tirẹ, nitori owo pọku ni a nta wọn. Owo ọja wa rọju rekọja ala. Bi o ba wa si ile-ọja wa "Ka mi, ka mi, ka mi" ni gbogbo wọn, bi o ba fẹ ja irọ wa, rin wa si ile ọja wa.

Iye owo wọn:—3d, 4d, 5d, 6d, fun ọkọkan; 2/6d, 3/-, 4/-, 5/6d fun mejila.

Ibikibi ti o ba ngbe ni *Nigeria* tabi ẹhin okun kọwe ṣọwọ yala ni ede Gẹsi tabi ti Yoruba si:—

E. O. AMBE & BROS,
38, Moloney Bridge Street, Lagos,
( *Lẹgbẹ awọn Oniṣowo A. J. Tangalakis* ),
Idumagbo, Eko.

## Ile Ita Egbogi ti Macaulay,

88, BROAD STREET.

Wabiwosi oriṣiriṣi Egbogi lo ṣẹṣẹ de fun wa ni tita: awọn bi:—ogun Egbo oriṣiriṣi, ogun Ẹda, ogun arun aṣiri, ogun Arẹmọ, ogun Onigbameji, ogun Aran oriṣiriṣi, ogun Lakuregbe, ati awọn ogun miran ti a ko le mã to lẹsẹsẹ.

Ọpọku-ọyọku ni owo wọn, awọn si jẹ bi idan.

Ọrẹ, ẹ lọ dan awọn Ogun wọnyi wo nibi ti a gbe nta wọn.

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.